AWỌN TO SE ORIRI... ...RE EṢIN LI EKO

ELETI OFE
A-NJU-WỌN KO SE WI L'EJO

VOL. VII No. 397 LAGOS (SATURDAY) ỌJỌ ABAMẸTA JANUARY 8 1955. IYE OWO ELETI ỌFE KỌBỌ MEJI

## Ikede

Awọn Ikede yi f u n gbogbo ẹnyin Ọlawe wa ati Asoju wa wipe, ẹni kọni ti owo ba sẹku si owo re ki o tete fi ranṣẹ nitori gbogbo ohun elo ti a fi nṣe iwe iroyin lo ti gbe owo leri.

Bakanna ti ko ba fi tire ranse ao da iwe rẹ duro ao si sa agbara lati gba owo wa ni owo re. Olotu.

## Awọn Ọmọ Ti A Bi Lose Yi

Gẹgẹbi ikawe ti o jade lati awọn ẹmọ ti a bi ti osẹ yi lati ibere ọdun 1st Jan titi 7th Jan 1955, gbogbo ọmọ ti a bi bi latin r... o ... ọmọ, Oloriire jalọjalọ.

# Awọn To Se Orire Ninu Ere Esin Li Eko

**Eko** Ninu aditu ere Esin ti awon egbe elere Esin yio sa loni (Lagos Race Club) awon ti oruko re mbe ni isale yi, ni awon ti o ti sorire ninu re. Enikokan ninu awon enia na yio je owo kabiti ni. Eniti esin tire ba ya gbogbo esin yoku ni yio je £950. Esin keji yio je owo nla. Be ni esin keta pelu. Owo ti o ba seku sile ni awon enia yoku ti o se orire yio pin. Iwonyi ni oruko awon to sorire na.

| | | | |
|---|---|---|---|
| No. | 002819 | Ayoka Samuel Oruko Esin ti won je | Danger |
| " | 007032. | Adesanmi Adebo | Sei Alah De |
| " | 012368. | Nat Oluwa | Idi-Oro |
| " | 001662 | O. T. Jibowu | Fear God |
| " | 008822 | R. Audiferan | Araromi |
| " | 015124 | Muyinatu Alaka | Alah De |
| " | 011876 | Adebiupe | Amar |
| " | 018917. | Aiyetoro Odewumi - | Mount Leban |
| " | 001578. | Y.O. Dawodu - | Attention Please. |
| " | 017748. | Ramotu Musa | Blue Demon. |
| " | 018673. | Ibikuule Alakija - | Funlose II. |
| " | 005365. | Olu Majekodumi - | New Comodore. |
| " | 002826. | Omiyele Cole - | Black Velvet |

Wo oju ewe kefa

## Ọlọla Ọbafemi Awolowo



Eniti a nwo yi ni Ogbeni Obafemi Awolowo okan ninu awon olotu egbe Omo Oduduwa ti o lo pari ote ati edekoyede ti o sele ni Ijebu Ode ti a si gbo wipe ote na wole bamubamu.

## Mo Ba Olomo Yo

**Iragbiji** Eniti o mu ... bimo, Ki o ba olomo yo. Ogbeni T. A. Bello ni Olorun fi omo rubutu ta a l... ti ... ko omo na jade lojo Saturday ... o koja l... yi.

Ese gbogbo awon Alufa ... pe sibi ikomo na, Lemomu ... si ke wutuba ... omo n... o si Fua ni oruko ..., M...a ... Saliha Atano. Oruko ... omo na a ma je Awawu Gbonju ... la.

Die ninu awon Alufa ti o wa sibi ikomo na ni Alufa S Idowu Alufa Bello, Malam Tijani, Adegbite Bello, Mustafa Babasale, Alufa Sanni Ajanasi, Egbe Iya Suna Iragbiji.

Lehin ti awon alufa pari tiwon tan ni Egbe Ajirowo ti nse egbe Baba Tunfulu wa gba ode kanri, ti nwon nnawo bi sekere. Die ninu won ni Ogbeni S. Ola Ige, B. Agboola, B. Akande, Alimi Okesola, Salami (Kaiyaoja Mo ba Olomo yo.

## Ogbeni Dokita Olorun-Nimbe



Eniti a nwo yi ni Ogbeni Dokita Olorun-Nimbe, on pelu iyafin Abiodun Ogundimu lo jijo kuro nilu Eko lati lo foju kan Oba obinrin nilu Oba, sugbon nigbati nwon pada de, nwon taku lati jihin emiremi ti nwon mu bo.



## THE NATIONAL BANK
### OF NIGERIA LIMITED.

Ile Ifi Owo pamosi yi
Nfi ona owo han eni
Bi o ba fe je onisowo pataki ao
ran o lowo nipa wipe ao to o
si ona ti o dara, ao la oju re
si Ona owo lati ilu Okere wa
Bakanna si ni a tun se iranlowo fun
gbogbo oja ile wa ti anta si agbaiye.

**ILE ISE WA NI EKO :-**

37, MARINA P. O. BOX 508 LAGOS

**AWỌN ASOJU WA NILU ỌBA NIYI**

**THE NATIONAL PROVINCIAL BANK**

(Overseas Branch)

**1. PRINCESS STREET LONDON E. C. 2.**

**THE COMPTOIR NATIONAL DESCOMPTE DE PARIS**

**8/13, KING WILLIAMS STREET. LONDON E. C.4.**


## Eniti O Pe Akintola Lejo Fara Soko

**Ibadan** Ogbeni kan ti a npe ni Lajide lo pe Ogbeni S. L. Akintola li ejo si kotu Ibadan, larapa o se ibo, ko se ibo. Akintola gba loya Fani Kayode Lajide si gba loya Olowofoyeku.

Nigbati aseko to, lati pade ejo yi, Ogbeni ti o pe ejo na ko wa si kotu, nwon ni ara re ko le, loya Kayode soro niwaju adajo wipe ejo ti nwon pe Ogbeni S. L. Akintola ko to suna rara gbogbo ohun ti o ni lati se ki o to se iwe ipejo, ko si okan ti Lajide se ninu re, o tun gbe ibe, o joko sile.

Nitorina on da moran wipe ki adajo fa iwe ejo na ya, nigbana ni loya ti Lajide dide o si bere ase lodo adajo ki on tun iwe ipejo na se.

Esun ti Lajide fi sun Akintola ni wipe o se ikede fun on, ibe ni o ba fa iwe ejo na ya, o wipe ki Ogbeni Lajide lo san poun mejidilogun ati sile mejidilogun owo irin ese fun Ogbeni Akintola.

## OJO 14th ATI 15th JE OJO ISINMI

IBADAN. Gomina Ibadan ti fi ase si wipe ki ojo 14th ati 15th osu Jan 1955 je ojo isinmi fun gbogbo awon osise ti Onisowo ati ti ijoba, kakiri nile Yoruba.

Sugbon ilu Eko nikan ni ko si ninu awon ti yio gba isinmi lojo na ni ile Yoruba.

## Qwo Te Qni Ala-pako Kan Li Apapa

**Igbologun** Lojo 25th osu Dec, 1955 ti ojo odun Keresi - mesi gan nigbati oko Marine kan mbo lati Badagry be ni rnami kan ti o 'ete ni waju won.

Ogako na Captain Pofi gbe iron lati yio si eraami na, sugbon o nfe ki oko tunbo sun mo eranmi na.

Nigbati oko na sunmo tosi ere o mi no ogako na pase wipe ki oko sunmo nigbana ni nwon ri wipe oni Alapako ni nwon gbe sinu oko nwon si gbe lo sodo awon Olopa awon si ju oni na si itimole

Iyalenu li o je fun awon olopa lati ri okunrin Egun kan joko ninu itimole pelu apoti kan, ega sopa bi lere wipe ki lo tirin ki o to de inu itimole ko le soro nwon bere orako re o dahun wipe Gbedegbe ni oa uje.

Nigbati oro na dewaju Adajo awon olopa so wipe awon oloko Marine lo gbe eranmi kan wa fi han gegebi o si ti je abami eranmi nwon gbe ju si itimole. Nigbati o di owuro oje keji awon ko mo ona ti okunrin yi gba de inu itimole Nigbati oa ei adajo ye ejo re sinu osu Jan 1955.

## Ko si Ilu To Talika To Libya

**Brazzaville** Awon agbajo egbe Onisegun ti egbe gbogbo agbaye ti a npe ni W. H. O. sofun wa wipe ilu Libya je ilu ti o talaka jojo si e meji to fun enia meta lati fi jeun lojumo.

Idi re ni wipe, ile gbigbe ni ilu na, ko odo ti o nsan ko si akuro tabi abata ko si adaguoomi beni ko si omi tutu bi ko se wipe Digbolokun ni omi t nwon nmu. ojo ko si ero ju igba kan tabi meji lo li odun kan.

Nipa bayi ise agbe ko se damn damn, ko si ise pataki nilu na. Arun igbe Orin ati Unigbameji po ninu ile Libya, ohun ti o si nfa arun yi wa ni wipe bi enia ba mu omi ti ko dara tabi ey ti a ti fose sino re yio ko arun, Bakanna ni iru arun yi wopo larin awon enia ti o ngbe eti odo nile Egypt.

Bi enia ba nsaba mu iru omi yi arun sobiya y o ma da oluwa re li amu arun yi si wopo ni apa ile America. Arun ti o buruju ti o tun mba awon eniti o ba nsaba mu omi buruku ni arun Arunpu.


## SECOND HAND CLOTHING

| | |
|---|---|
| Women's long Coats | 2/- |
| Women's Short Coats | 1/- |
| Women's Dresses & Frocks | 1/- |
| Women's Skirts | 1/- |
| Costumes | 5/- |
| Men's Raincoats | 3/- |
| Men's Jackets | 1/-6d |
| Men's Waiscoats | 6d |
| Men's Felt Hats | 1/-6d |
| Men's Khaki Greatcoats | 20/- |
| Men's Ex-Service Overcoats | 10/- |
| Men's Overcoats-Civilian | 5/- |
| R. A. F. New Side Caps | 1/- |
| Men's Suits | 20/- |
| Ex-Army Blankets | 7/-6d |

Noless than 250 supplied.

We have also Radiograms £10: 0s: 0d Secondhand Pianos £10: 0s: 0d Organs £10: 0s: 0d

Prices quoted ex-warehouse. C.I.F. charges extra. Immediate attention. Writetfor full price list Enquiries invited.

**H. NEWMAN & Co (MERCHANTS) LTD.**

88/92 Elizabeth Street, Manchester.. 8. England.

Cables: "Recovery" Manchester


## Esin Imale Li Qlorun Fe

Olotu

Bi mo ba ipe ki ndake ki nma wo awon elesin Igbagbo nwon ko ni jeki nsimi, eso ni awon o ma gbe mi li ereke jo.

Oro ti mo se fun Ogbeni Ajala nigbati mo sokun wipe ko si loju ona esin otito wipe ki on gba esin Imole. Mo pe ni Alufa Eni owo, sugbon o tako wipe ki nma se pe won be mo.

Jesu so fun awon omo ehin re wipe, ki lo si arin awon Jew ati omo Israel, kede ihin rere fun won sugbon ki e mase lo soju ona awon Keferi. Eyi fi han wipe, Olorun ko ran Jesu si gbogbo aiye bikose si Israel.

Sugbon awon Angeli orun papa eyin Anobi Muhamad. Nitorina Ajala wa wo esin Imale ki ile to su.

Imam Ajakuta

### AJALA ALAJA NIBON PANTIWA ?

Olotu,

Mo ri iwe kan gba lati odo Ogbeni Ajala ara Dandume, ninu eyiti o so bayi wipe Lemomu ni bi on wa wo esin Imale.

Idahun mi fun Ogbeni Ajala ni wipe Onakansoso li o ntoka si Orun, isina ni eyiti o ku. Ona kansoso ni esin Imale.

Gbogbo oro ti o mbe ninu iwe mimo ti Kuran je oro lati enu Olodumare wa, ti ko si yipada si eyiti Olorun so jade titi di oni sugbon oro inu Bibeli, op lopo re, ni a ti yi pada si eyiti Olorun so jade.

Ni apere, Psalm 9. bi o ba nka a lo, ninu Bibeli ti 1928 iwo yio ka Oruko yi Higaion Bi o ba je wipe oro Olorun l dode ni oro inu Bibel ese ti oro yi fi sonu ninu re.

Eyi ni moro ki nto pe Ajala sin oko igbala wa, Idi oro n y o, iwo Ogbeni Agbaje.

Lemomo Ajakuta.

## Idahun Si Ibere Agbaje Ni i

Olotu,

Gbami laye ati dahun si ibere Ogbeni Agbaje. Eniti o ye ki o mu owo pupo ni elewe Taba.

Nitoripe koko ko le di ero isana ewe ko le di eru sugbon elewe taba le ja ewe taba ro si ohu

2, Kini oro awon Alakuko ti ri o?

Emi ni
D. Ajala
Ara Dandume





GIDAN GOLDIE, KANO

**THE UNITED AFRICA COMPANY LTD**



**NOW, AVAILABLE**

BUGLES, BEDSTEADS PAINTS DISTEMPERS, SAFES Etc.
Just write, Call, or Phone 21372

**IKORODU TRADING COMPANY**

20/28, Balogun Street, (P. O. Box 395) Lagos.
AND
NEW COURT ROAD IBADAN




EBUTE TAKORADI TITUN NIBITI A NFI IGI GEDU NIKQ

Ilu Takoradi ti di ebute pataki kan ni apa Iwo Orun ile Africa, nitori ibi ti oko ngunle si, ti asese ko pari laipe yi nmeki a tunbo ri aye ko igi gedu niko, a sope gidigidi fun idiko titun yi. Simenti Burham ni a fi ko, nitori on lo lagbara julo ni gbogbo agbaiye. O to iwon adorin odun ti a ti nlo Simenti yi nile enia dudu, on ni a fi ko opolopo ile nlanla ni ilu wonyi, eyiyi je iranlowo pupo ninu idagbasoke ile enia dudu.

BURHAM
PORTLAND CEMENT

BURHAM BRICK LIME AND CEMENT CO. — BURHAM WORKS — TRADE PORTLAND CEMENT MARK — LONDON

**Always Read And Advertise In Eleti Qfe**

# Irohin Lati Ilu Okere

## Tokotaya To Sowo Aiyederu Wo Ewon

**Eko** Okunrin kan ti a npe ni Animashaun ati obinrin kan ti a npe Sekete pa imo po lati ma lu awon oyinbo Onisowo Oke okun nijibiti, owo Olopa te awon mejeji, won si da seriya fun won.

Ohun ti nwon se ki owo to te won ni wipe oyinbo Onisowo kan ti o nta aso Siliki ati aran ni nwon lu ni jibiti apoti aso aran mejo tobe nigbati oyinbo na gbo idi oro yi nse li o kawo le ori ti o si sokun lo ba ijoba ilu Aguda. Nigbana ni ijoba won kesi ijoba Eko ki owo to te awon Onijibiti mejeji na.

Awon Otelemuye bere lowo awon Onijibiti mejeji nwonyi kini oruko ti nwon fi nsowo Eyi ni oruko won na. Commercial Clearing House Trade Inquiry and Finance Ltd.

Nigbati nwon ni ki awon odaran na lo mu iwe oruko egbe won lodo ijoba wa o di wo mi ki nwo o ni adajo ba ju okunrin si ewon odun marun ati obinrin si ewon odun meta.

## Oniwe Irohin Kan Segbe Sinu Omi

**Okun-Alasia** Lojiji ni a gbo irohin iku ogbeni Ajibola, eniti o nsise labe iwe Irohin kan ti a npe ni Challenge ni Okun-Alasia.

Bi a ti gbo irohin na si ni wipe li ojo 27th osu Dec 1954 ni ologbe yi lo we li okun-alasia on pelu omo re ati aladugbo re kan. Bi nwon ti nwe lowo, ero po li eti okun laseko na, beni isan lile ba mu omo Ajibola ati ekeji re.

Ologbe Ajibola yara lo sibe lati gba awon meeji la, beni isan ba mu on na paapa, eni eleni miran li o gba omo ati ekeji re la, sugbon Ajibola di ologbe.

A gbo wipe ologbe Ajibola yi je omo ti a bi ni Oro Ago nile Ilorin, ati wipe labe ijo S. I. M lo ti ko iwe. A fi eyi ki awon ara ati ore wipe nwon ku afeku.

# IRORA ORIKERIKE

## A ma so ni di Alara gigan tabi Aro



Nigbati Kidirin tabi Olo inu re ko ba sise re to o ye ki aran lowo. Bi beko iwo papa yio mo funra re pe ewu mbo. Ninu awon ewu na ni irora orikerike je okan o le je wipe olo-inu re ko sise re to nipa sise eje re.

Egbogi DE WITT yi a se nipataki lati jeki Olo-inu re bere si sise re iranlowo ti yio se fun Kid'nrin ni lati koko wo gbogbo irora orikerike na fuye. Gbogbo awon eje ti ko sunwon ti o mbe nibe yio kuro. Opolopo iwe ni a ti rigba kakiri aiye ti,

awon enia ti dupe fun wa latari egbogi DE WITT'S yi ti nwon si ri alafia ara won gba Boya iru egbogi yi le se rere fun o si dan wo fun iyonu tire lobere ni sobu egbogi Egbogi DE WITT,S yi a se ni pataki fun:-



ARUN ARUNGUN WODIWODI EHIN DIDUN. IRORA ORIKERIKE LAKUREGBE, ati gbogbo IRORA

Ohun ti o dawa loju ni wipe egbogi DE WITT'S je eyiti a so tonitoni gbogbo ohun elo re lo si mo gara.

**DE WITT'S PILLS**
for Kidney and Bladder Troubles


## Awolowo Fe Wuye

**Ibadan** Irohin kan wa wipe Ogbeni Obafemi Awolowo eniti Oba Alake Sir Ladapo Ademola fi je oye Lisa ti Ijeun, ti Oba Akarigbo Ijebu Remo tun fi je oye Asiwaju gbogbo omo Ijebu Remo ngbaradi nisisiyi lati se iwuye ti oye mejeji ti o ti je na nigbati o ba di ... ojo 6th osu Jan 1955 Awayewuye iwuye na yio gba to ose kan. Ni ilu Ikenne ni ao gbe se ayo ti iwuye na.

## Esora Yin Nibi Jibiti Ile India

**Accra** Asoju ijoba ile India ti o mbe nile Agenyin lo se ikede yi wipe ijoba ile India ko ninu didun si origirisi tira, oode, tabi adamodi egbogi ti nwon npolowo re kakiri lati ile India wa.

Isu ijoba yi yo dun bi awon enia ba l. se iranlowo nipa fifi iru iwe aiyederu ba ranse si India Commission Private Post bag Accra ti tori ki a ba le ni ssandima lati fi ba iru awon enia be rojo.

## Igbimo L.T.C. Fi Kun Owo Omolanke

**Eko** Igbimo ... [illegible] ... meta ... Omolanke Ikeja ... eniti o ba ofe keke ... Omolanke ... odun ... [illegible] ... awon ti ijoba ko ... ma ose Awokoke ...

Iye owo awon ... [illegible]

1. Basikulu Elese ... 10/- lodun.

2. Keke elese ... o ni ese iru ti moto ... a fi awo omo kekere ... wosisi ninu ... fun ... (Pram) £4,00 lodun.

3. Keke Rere (Rickshaw) ... [illegible]

4. Keke ... [illegible] ... meji tabi meta ... iru ti moto £4

5. Keke Elesin ti a ko fi ... £2.

## BOY'S COMPANY THE NIGERIA REGIMENT

Attention is drawn to the Press Release published in the Lagos daily papers in December.

The Selection Board will visit Lagos and interview candidates for selection on Wednesday 16 March 1955.

Candidates to be eligible for interview must be not less than 13 years old and not more than 14 years old on 1 April 1955.

Any Lagos boys wishing to be considered for the Boy's Company should apply at the office of the Chief Administrative Officer, Lagos, before 31 January and bring with them a birth certificate or statutory declaration of age.

## Talo Ni Ogun Poun Ti Nwon Da

**Eko** A gbo irohin wipe rogbodiyan kan fere selo ninu Mosalasi jimo nipa oro ogun ko se ogun poun

Balogun imale so wipe on ni eniti o fi ogun poun ran ogbeni kan nise wipe ki o ba on ko owo na fun awon Jonmo. Sugbon, ogbe ni ti a fi owo ran na so wipe ti on ni ogun poun na.

Ion wa yio dun bi awon jonmo ba le fi ye wa, Tani eniti o ni ogun poun na. ti a fi ba o'uwa so wo yi?

## Shakleford Di Ologbe

**Accra** Anu se ni jojo lati gbo irohin iku, Ogbeni Winter Shakleford Olori Oniburedi Eko, ti o si ti nse okan ninu awon Honorable member of Legislation Council ni iwon odun 1926 ti o si di olokiki nipa Buredi re nisise,

Ologbe yi ta ilese re ati owo Buredi re fun awon egbe African Development Corporation, o si lo joko si Oke Okun.

Sugbon o ti fi ohun silo wipe nibikibi to wu ki on ku si, nile Nigeria ni ki a gbe oku on wa sin.

Pataki omo Oloku yi ni Dokita Olorun-nimbe, nitoripe Ologbe na

## Igbesi Aiye Olola Sir Kitoyi Ajasa

Ogbeni Edward Macauly dagba pupo ki o to lo ko Ise Loya nilu Oyinbo, o si to eni odun mertadiludorin nigbati o yege ninu ise loya Nigbati o pada de si Eko ni odun 1893. o yi oruko re pada si Kitoyi Ajasa Ijoba fi se okan ninu awon Asoju ilu Eko fun igbimo Legislative Council ni odun 1906. O di okan ninu awon igbimo ile Nigeria ni odun 1914. Odun 1914. On ni eniti o da iwe irohin kan ti a npe ni Nigerian Pioneer sile on na ni Olotu iwe irohin na ni 1914 pelu,

Ijoba yan l. ti se asoju fun ilu Eko, Epe ati ilu Badagry ninu igbimo Legislative Council ni odun 1923. O joye O.B.E. ni 1927. O si tun joye K.B.E. ni 1929.

Nigbati ijagboro be sile nilu Aba nibiti larapa oro owo ori ti o di ogun ti awon olopa ni lati yinbon pa awon obinrin ilu Aba. Ogbeni Sir Kitoyi Ajasa je okan ninu awon Amofin ti ijoba yan lati lo wadi rogbodiyan na ni 1930,

Sir Kitoyi Ajasa ni Akapo gbogbo owo ti ijoba C.M.S. Anglican Diocess. On ni eniti a npe ni Oluwa ati Alase Afin Gods tone House Ile re wa ni Odan Force Road ni Eko.

je okan ninu omo egbe Demo ti Nimbe nwon sin ku re lojo 2nd osu Jan 1955.

# PUBLIC NOTICE

Applications are invited for the post of Marketing Officer, Department of Marketing and Exports. Particulars in Government Notice No. 2226 in Federation of Nigeria Official Gazette of 30th December, 1954. Applications to Secretary, Public Service Commission, Private Bag No. 2586, Lagos. Closing date 29th January.

## MARINE DEPARTMENT NOTICE NO 49 OF 1954

### SAPELE–BENIN FERRY SERVICE

From the 14th January, 1955 until the 14th February 1955, N. M. F. "Swan" will be taken out of service for annual docking and repairs.

F. W. SKUTIL
DIRECTOR OF MARINE.

O bere lati oju ewe kini

| | | |
|---|---|---|
| 006507 | J. Odubanwo – | Madone |
| 013263. | Yemisi Balogun – | Beleve Alah De |
| 010124. | J. Munis – | Dodo |
| 013954. | S. Durojaiye – | Mount Farid |
| 003748 | Olatunji Oriola | Red Velvet |
| 005351 | Okoye | Dan Barka |
| 016723 | Wilcox | Presto |
| 017209 | Odo of Bonny | Gazal |
| 012420 | Tinubu Owodunni | White Ghost |
| 007488 | I. Kekere | Torbal |

## Dokita Ka Fi Ise Sile Boya Aiye Yio Pare

**New York** Irohin kan wa lati Amerika wipe okan ninu awon oluko ile eko kan fi ise re sile ero wipe aiye ufe dopin.

Ohun ti awon oluko agba naa ... wipe, awon omo ile eko ... gbogbo eni ti ... lati ojo idajo ku ... dede.

Oluko agba na tun so wipe, bi o ba fe fi ... ki awon gba fun ... pe ... yi. Oluko ... wipe bi o ba di ojo Ojo 21st osu Dec 1954 loje Atalata ... aiye yio pare.

A gbo robio pelu wipe Oluko na ... awon ohun ini re ... ti o gun ori oke ... si nipo igbo lati fi oju ri bi aiye yio ti se pare. Oruko oyinbo na nje Dokita Charles Laughead.

# FOR SALE

1 Second Hand MORRIS 8 in good running condition.

Apply:-

**Thompson Taju**

17 HOLO STREET LAGOS

Between 4—6 p.m.


# REDIFFUSION

LISTENERS

**E**NJOY

**D**AILY

**I**NTEREST AND ENTERTAINMENT

**F**ROM 6 A.M TILL 11 P.M

**U**NRIVALLED

**S**ERVICE ALREADY

**I**NSTALLED IN

**O**NLY 2 YEARS IN NEARLY 40,000

**N**IGERIAN WESTERN REGION HOMES



## HAPPINESS SUPREME!




"Ma gives me 'BANWO' and so, I'm strong, robust and healthy."

Buy BANWO for your baby.
Large bottle ... Small bottle ...
THE AFRICAN STORES ... and branches


## Sekiteri Agba Mbo Ni Nigeria



**London** Sekiteri agba nilu Oba, eniti o gba ipo lowo Ogbeni Oliver Lyttleton ti a npe ni Lennox Boyd, yio dakan wa si ile Nigeria.

Yio ba oko ofurufu gunle lojo 13th osu Jan 1955. Li ojo 15th osu na yio fo lo be ilu Tiko ati Buea ... agbegbe ile Kameru.

Lojo 16th osu yi yio lo be ilu Kalaba ati Portharcourt wo, yio si gba ona moto lo si Enugu lati be ilu nawo, yio si ya ni ilu Owerri

Yio fo lati Enugu lo si Kaduna, yio lo be ilu Sokoto ati Kano wo yio si fo lati Kano lo si Ibadan yio wa nile Yoruba titi yio fi ba moto lo si ilu Eko ki o to wa gbera pada si ilu Oba lojo 29th Jan 1955.

## Asotele Fun Odun 1955 Lati Ile Egypt

**Egypt** Okunrin aafaa ara Egypt kan ti a npe ni Muhamed Alli Feki lo so asotele yi nipa awon ohun ti yio sele ni odun 1955 ti a wa yi.

O so bayi wipe alaisiyi ko si ogun tabi ote olukuluku wa ni alafia sugbon aigbati yio b... fi te akoko osu August. Ogun jija yio tun gbaiye kan ao ma gboro nipa ogun ati irokeke ogun, sugbon ogun na ko nipe pari.

Rogbodiyan yio ma be ... larin awon Jamani ti o mbe labe ase Resia pelu opolopo omo ogun alanla.

## Enjoy Your Own Songs

SUNG BY YOUR OWN PEOPLE IN THE WAY YOU LOVE MASTERLY RENDERINGS OF TRADITIONAL AFRICAN MUSIC IS YOURS ON




OBTAINABLE FROM:

**The Association Of Nigeria Gramophone Dealers**

THROUGHOUT NIGERIA

Printed & Published by The Union printing and Publishing Company, 62 Kokoro Street P. O. Box 467 Lagos, Phone 23370